THE EDITOR IMOLE OWURO
16/4/77
IBADAN.
21 APR 1977

WEEKS 38&39
Kongi WK 37
16 17 19
Wk 38
3 11 20
Asiko BK WK 37
6 24 27 29
Wk 38
3 4 25 26
Ross Wk 37
2 & 10
WK 38
41&49

Imọlẹ Owurọ

ẸSIN ỌRỌ WA: IMỌLẸ DE OKUNKUN PARADA!

SAMCO OF NIGERIA
WK 38
NAP 14 18 33
Perm 13 14 18 33 35
My Address ?
Not ressesary.
A ways meet me in
Imole Owuro
Every Saturday
12 27 43

Independent Paper Vol. X NO 793 S[ATU]RDAY APRIL 16 FRIDAY APRIL 22 1977 10K. (KOBO MEWA)

# 'GBOMOGBOMO FE JI DOKITA GBE' NI IJEBU

IROHIN lati ilu Ijẹbu-Ode ni Ipinlẹ Ogun fi ye wa pe, aṣiri awọn enia kan ti nwọn pe ni "Eegun ilu" nilu Ijẹbu-Ode ti tu lati ji Dokita ile iwosan ilu Ijẹbu-Ode gbe lọ.

Awọn "Eegun ilu" na ni a gbọ pe nwọn fẹ ṣe eyi ki Dokita na ma ba le roju ko ododo abajade iwadi l'ori ẹsun pe awọn enia na ba ọmọbinrin ti ko tii to mọ ọkunrin sun.

Irohin sọ pe lehin ti awọn "Eegun ilu" na ti huwa na tan, ni awọn obi ọmọ obinrin na lọ fi ẹjọ sun awọn Ọlọpa.

Nitori eyi ni nwọn sọ pe awọn enia na fi fẹ ji Dokita na gbe ti nwọn si gbimọpọ pelu Dẹrẹba ti nwakọ Anbulansi ile iwosan na pẹlu awọn oṣiṣẹ kan nile iwosan na.

Bayi ni awọn enia na gbe Takiṣi kan lọ sile Dokita na. Nigba ti nwọn debẹ, nwọn ni awọn oṣiṣẹ ile iwosan na l'o jade kesi Dokita na pe, iṣẹ pajawiri kan ti delẹ nile iwosan. Takiṣi ni awọn wa fi

(Woju Ewe Kẹjọ)

## IDILE LAOSEBIKAN DUPE FUN IBANIKEDUN

NI orukọ gbogbo Ọmọ, Ọmọ-ọmọ, Ẹgbọn, Aburo, Gbogbo Ẹbi ati idile Laoṣebikan lapapọ: A dupẹ pupọ lọdọ gbogbo enia ni ẹlẹgbẹjẹgbẹ, awọn ọrẹ, awọn Ijọ ni Ibadan ati Ogbomọṣọ; awọn olufẹ gbogbo lati ilu bi Iseyin, Eko, Agege, Tapa via Ogbomọṣọ, fun ẹmi ifẹ ti nwọn fi han nipa ibanikẹdun lọpọlọpọ ati inawo wọn fun awọn ọmọ oku ni akoko ayẹyẹ ikehin ti nwọn ṣe fun iya wọn, Ọladoyin Aṣabi Alabi, eni ti o fi aiye silẹ ni ọjọ kẹwa oṣu kẹta ọdun yi (10/3/77) ti a si ṣe isinku rẹ ni Ogbomọṣọ ni ọjọ kẹrindinlọgbọn oṣu kẹta ọdun yi (26/3/77).

Awa mọ riri ọpọlọpọ ẹbun owo ati awọn nkan miran ti ẹ fi fun awọn Ọmọlooku ni akoko yi. A si tun mọ riri akoko ti ẹ fi silẹ ni akoko eto na. Ẹsan rere ni Ọ'ọrun yio san fun nyin o. Ọjọ yio jinna si ara wọn; ọmọ rere ni yio gbehin ẹnyin na o.

Ẹ ṣe e pupọ.

E. O. LAOṢEBIKAN
(Fun Gbogbo Ẹbi)

## Ina ran l'Eko

IJỌBA Ologun Ipinlẹ Eko ti gba dukia ẹgbẹẹgbẹrun Naira ti awọn ogalọga iṣẹ Ijọba kan l'aiye Ijọba Ọgagun Mobọlaji Johnson fi ọna aitọ kojọ.

Eyi jẹ abajade Igbimọ oluwadi kan ti Ijọba Ipinlẹ Eko labẹ Ogagun Adekunle Lawal gbedide lati yẹ iṣẹ wọn wo.

Awọn enia ti oran na kan ni Alakoso Eto Isuna nigba aiye Ọgagun Mobọlaji Johnson, Amofin I. S. Adewale, Akọwe Ijọba na, Ọgbẹni F. C. O. Coker, Ọga ile iṣẹ akoso eto owo nigbana, Durosinrin Eti.

Ọga iṣẹ miran ti ọrọ na tun kan ni, Ọgbẹni J. O. Adeyẹmi - Bero, Ọgbẹni F. A. Yousuf, Oloye Y. A. Yusuf, Ọgbẹni J. W. Ayẹni, Ọgbẹni Adeyeri Ogunsanya ati Alhaji S. A. Jẹnmi. Awọn meji yoku ni Ọgbẹni Latif Adejumọ Adisa ati Ọgbẹni Hamzat Abiọdun Subair.

Iwe ikede ti o jade l'ori ọrọ na salaye ibi ti gbogbo dukia na wa. Ọpọlọpọ ile, ile ati ipin idokowo ti ọpọ ninu wọn ni ninu awọn ile iṣowo kan ni o wa ninu dukia ti Ijọba gba na.

## IKEDE PATAKI

EYI ni lati sọ fun gbogbo enia pe, Ọgbẹni JAMES ỌLAYIWỌLA AJIBOYE, eni ti ẹ nwo aworan rẹ ni isalẹ yi, ti o ti fi igbakan jẹ ọkan pataki nibi ile iṣẹ ARẸ-AGO SUPERMARKET, MOTORS and SAWMILL ni Ṣekooni nilu Ogbomọṣọ, ki iṣe oṣiṣẹ wa mọ o. Nitorina, ẹnikẹni ko gbọdọ ba a da ohunkohun pọ mọ l'orukọ Ile Iṣẹ wa ti a darukọ nni. Ẹnikeni ti o ba ba a da nkan pọ l'orukọ wa; iru eni bẹẹ ṣe e si adamu ara rẹ ni.

Ati wi pe, ati tun ṣi ẹka Ile Iṣẹ wa miran si Ọpopo Aarẹ-Ago lodikeji ile Abiye Col. Ibrahim Taiwo, Oja Jagun, Ogbomọṣọ lati 7/4/77 fun irọrun gbogbo awọn ti o wa ladugbo na ki nwọn ma ba maa ṣe wahala lọ si ọna jijin mọ ki nwọn to ti ọja ti nwọn nfẹ ra.


James Ọlayiwọla Ajiboye

Oniruuru ọja ni enia le ri ra nibẹ ni owo pọọku-pọọku. Nitorina, maa lọ sibẹ lọ raja tirẹ lati oni lọ. Ma ṣe jafara.

I. A. DAVIES
Oludari Ile Iṣẹ

ARẸ-AGO SUPERMARKET, MOTORS & SAWMILL, OGBOMỌṢỌ.

# ATIORO OMO ATIALA

## Oore t'o dara (5)

A ti sọ fun ọ pe,
Gbogbo oore
T'o ba la agbere lọ
Ki i ṣe oore t'o dara;
A si sọ ẹwẹ
Pe, oore ṣe-ka-ri-mi
Ki i ṣe oore atata;
A si nkilọ ọran
Pe, k'a ṣọra gidi
K'a ma ṣ'oore
Ti ko dara.
Ara oore ti ko dara ni
Ki enia ṣoore l'aabọ
Ki enia ṣoore tan
Ki o maa sinregun
Ki enia ṣoore ti ko tọ
Ki enia ṣoore oju aiye,
Ki enia ṣoore tan
Ki o loṣo ti i,
Ki enia ṣoore
Nitori k'o le ri ẹsan
L'ọdọ ẹni t'o ṣe loore.
Iwọnyi ki i ṣoore t'o tọ.
Oore buruku ni,
Ko si yẹ fun
Ọmọluabi enia
Iya Ibeji ti njo,
Iwọ ti o ri
Oloriṣa enia
T'o tamọra
T'o si nbeere ẹbun;
At'iwọ t'oo r'ẹlẹsin
Ti ko l'abuku arun
T'o ntọrọ saraa kiri;
Bi o ba ṣe wọn l'oore,
O ku aṣedanu.
Aanu a maa ṣe mi
F'ọmọ enia
Ti nbẹ l'ori ilẹ
Ti ki i ronu denu,
Nitori:
Nwọn a maa ṣoore si
Ibi ti ko ni i l'ẹsan;
Ọkan wọn a si balẹ
Nwọn a maa ro pe,
Oore awọn yio l'abọ.
O tun ku t'a a ti i wi
Gbogbo ẹni ti ngbọ.
Ẹni a wi fun
Pe, ki o ma daran
T'o kọ, ti ko gbọ;
Ti a kilọ ọran fun
T'o kọ lọpọlọpọ igba;
Ti a si nyọ l'ọfin
Ti a si nkilọ fun un,
Ti o kọ ikilọ
T'o tun npada
Sinu ọran nigbakugba;
Gbogbo ẹni
T'o ba nmu owo
T'o ba nyọ iru wọn l'ẹjọ
O nnawo anadanu ni
Enia t'o ba si lakaka
Ti nlo ẹsẹ
Lati yi idajọ otitọ
Ki iya le jẹ olododo
Ẹni t'o ba ṣe
Iru iranwọ eyi,
Oore rere kọ lo ṣe,
Ẹṣẹ l'o gba.
Iwọ ti o kọkọ gori ọmọ
na
Ki o to gb'ọmọ s'iṣẹ;
Iwọ ti o ba a sun,
Ki o to gbe e s'ipo t'o
beere,
Oore kọ l'eyi rara,
Ẹṣẹ l'o gba s'ọrun rẹ
O ko ṣoore ẹtọ,
Ẹṣẹ l'o gba.
Iwọ ti ẹ jọ ṣawo
Pe, bayi bayi
L'ẹ o ṣe b'o ba ya
Ti o wa gbẹhin ọrọ
Ti o lọ tu aṣiri igbimọ
Oore kọ l'o ṣe f'oni—
tọhun,
Ẹṣẹ gidi ni,
O ko ṣoore ẹtọ,
Ẹṣẹ l'o gba.
Melo l'a o ka,
Melo l'a o wi
Ninu ọpọ oore gbogbo
T'ọmọ araiye nṣe
Ti ko si tọ,
T'o rọ mọ kiki ẹṣẹ?
Ẹda ko si mọ,
Ẹda ngbẹkẹle e
Pe, oun nṣiṣẹ oore!




Gbogbo iru oore bayi ni
Ọmọ enia nṣe l'aiye
Ti nwọn ngbẹkẹle
Ti nwọn sọ pe
Awọn nṣe oore;
B'enia ba ngbẹkẹle
Iru oore bayi,
Ara rẹ l'o ntan jẹ
Nitori Ọba Odumare
Ko ni i san aarọ
Fẹni ba ṣe 'ru rẹ duka.
O tun ku, koi tan
Gbogbo janmaa wa.
Ẹni t'o ri alagbe
Ti ko fọ l'oju
Ti ko di l'eti,
Ti ko yarọ,
Ti ko d'arugbo,
Ti ko labuku arun;
Ẹni ba gbiyanju
T'o ṣe 'ru wọn loore,
Oore buruku l'o ṣe
Iwọ ti o ri
Oore aitọ,
Oore ti ko le l'abọ!
Bi a ba r'enia
Ti nṣe 'ru eyi pata
Ẹ jẹ ko tete tun
Ero rẹ pa gidi
K'o tete jawọ
K'o ma ṣoore
Ti ko l'abọ.

ỌLỌLA ATIORO

# Arisemase fi ewon jura

ILE—ẸJỌ Ibilẹ kan nilu Biida, ti ju awọn ariṣẹmaṣe meje k an si ẹwọn oṣu kọọkan fun jijẹbi ẹsun ọlẹ-ṣiṣe.

Ni ọsẹ ti o kọja ni Adajọ ju awọn enia na s'ẹwọn nilu Biida.

Ninu ọrọ rẹ ki o to ju awọn ọdaran na sẹwọn, Alhaji Aliyu gba awọn ọdọmọde niyanju lati jawọ ninu iwa ọlẹ. Adajọ na sọ pe, bibẹẹ kọ, ẹnikẹni ti nwọn ba mu wa sile ẹjọ na ti o si jẹbi ẹsun ọlẹ-ṣiṣe, yio f'imu danrin l'ọgba ẹwọn

Nigba na ni Adajọ na paṣẹ pe ki ọkọọkan awọn ọdaran mejeeje na lọ fi ẹwọn oṣu kọọkan jura.

## Abajade Idanwo Bibeli

IWỌNYI ni orukọ awọn enia ti o ṣe dara-dara ninu Idanwo Bibeli ti o jade ninu Imọlẹ Owurọ 19/3/77.

MARAARUN

Awọn enia ti o gba maraarun ni: Ribẹka Adegbitẹ lati Ogbomọṣọ, Oluṣọla Alaba lati Ibadan, R. A. Ayanwale lati Ogbomọṣọ, J. P. Ajiboye lati Eko, S. A. Olaogun lati Ogbomọṣọ, Paul Agboọla lati Ibadan, Abiọdun Ladimeji lati Surulere, Eko, S.A. Abidogun lati Ogbomọṣọ, Sunday Akanbi lati Oṣodi, Eko, J.A. Ṣangotọpẹ lati Ogbomọṣọ, Joseph Larewaju Ṣomolu — Eko, Samuel Afọlabi lati Ogbomọṣọ, Oseni Musitafa lati Ọyọ ati Josiah Korede lati Ogbomọṣọ.

MẸRIN—MẸRIN

Awọn enia ti o gba mẹrin-mẹrin ni Sunday Olukẹhinde lati Ogbomọṣọ ati Aarinọla Amọpe lati Ibadan.

IDAHUN IBEERE

Iwọnyi ni itọkasi idahun awọn ibeere na.

1. Nahumu Ori 1 ẹsẹ 7
2. Nahumu Ori 1 ẹsẹ 11
3. Nahumu Ori 2 ẹsẹ 5
4. Nahumu Ori 1 ẹsẹ 2
5. Nahumu Ori 2 ẹsẹ 2

IDAHUN TITUN

1 Nibo ni Tẹsalonika ti sọ pe, Oluwa yio sọkọlẹ lati ọrun wa?
2 Nibo ni Tẹsalonika ti sọ pe, Ọjọ Oluwa nbọ wa bi ole?
3 Nibo ni Tẹsalonika ti sọ pe, Ẹ maa gbadura ni ọsan ati ni oru?
4 Nibo ni Tẹsalonika ti sọ pe, Ẹ maa gba ara nyin ni iyanju?
5 Nibo ni Tẹsalonika ti sọ pe, Ẹ maa wadi ohun gbogbo daju?

Ẹ tete fi Idahun nyin ṣọwọ si Onidanwo Bibeli ni Adirẹsi isalẹ yi:

FUN TITA

Iwe: Ibeere Ati Idahun Inu Bibeji Ati Adura Ojoojumọ (English & Yoruba) ti jade fun tita. Fi Naira kan ranṣẹ si:

Apostle K. Kobiowu
(Onidanwo Bibeli)
S2/81 Ọranyan Sreet,
Ibadan.

## Lati Owo Karimu Kobiowu

# Afolabi jade laiye

NWỌN ti kede iku Alagba Adeyemi Afolabi ti agbo ile Aarẹ—Ago nilu Ikirun.

Ọmo idile oye Adedeji ni oloogbe na iṣe, o si lo opolopo odun aiye ki o to f'ilẹ bora bi aṣọ.

Ọpọ omo ati omoomo l'o gbẹhin rẹ gẹgẹ bi a ti gbo. Ara won ni Iyaafin Esther Wẹloye Ọlatunde, Ọgbẹni Ọlapade Ismahi Afolabi ati Ọgbẹni Salawu Afolabi.

Nwon ti sinku rẹ nilu Ikirun.

# 5&7

# 2 10 43

## Igi wo pa moto

ENIA kan l'o ku ti awọn meji miran si farapa ninu ijanba mọto kan ti o ṣẹlẹ l'ọna Oṣogbo silu Ikirun laipẹ yi.

Onirohin wa ni ilu Ikirun, Ọgbẹni Lasisi Ogunṣọln sọ pe, nigbati ọkọ akẹru na nbọ ni igi kan deede wolu u mọlẹ nigba ti iji nja ki ojo diẹ to rọ l'ẹnu ọjọ mẹta yi to rọ.

O ni lẹsẹkẹsẹ ni enia kan ku nibẹ ti enia meji miran si farapa. Nwọn ti gbe oku oloogbe na lọ si ile iwosan ilu Oṣogbo fun ayẹwo, nwọn si gbe awon enia ti o farapa lọ sile iwosan kanna fun itoju.

Onirohin wa so pe, bi nwon yio ku, bi nwon yio ye ni nwon wa nile iwosan na. A gbo pe awon Ọlopa ti bẹrẹ si i wadi ki l'o fa iṣẹlẹ na.



WOLI S. I. OWOẸYẸ
Oniwaasu Naa.

# Akede ọna Iye

ONAKANSOSO SI IYE AINIPEKUN

# A o re agberaga sile (I)

"BI Oluwa tilẹ ga, sibẹ, O juba awọn onirẹlẹ; ṣugbọn agberaga li O mọ li okere rere:" Orin Dafidi 139:6.

Iwaasu wa t'oni duro lori Igberaga. Iwa igberaga jẹ ohun buburu ninu aiye, eyi ti o buru niwaju enia ati niwaju Oluwa, ti ko si yẹ ki ẹnikẹni gba l'aye ninu ọkan wọn. Ẹnikẹni ti o ba gba igberaga l'aye ninu ọkan rẹ, ọta Ọlọrun ni.

Gẹgẹ bi a ti wi, ohun buburu ni igberaga iṣe. Ọpọ idaamu, iku-ojiji, arun, isansa, ole, irọ ati bẹẹbẹẹ ti nbẹ ninu aiye l'oni ni o jẹ pe, igberaga ni o fa a.

Ọpọ ni ẹmi rẹ ki ba gun l'aiye yi gẹgẹ bi ipinnu Oluwa si wọn ṣugbọn ti igberaga ko ni i jẹ ki nwọn pẹ ninu aiye.

Ọpọ arun l'o dimọ igberaga. Diẹ ninu rẹ ni, agbana ati abuku. Nipa bẹẹ, ohun ini yowu ki onigberaga le ni, ko ni i niyi pelu ohun ini na.

Iru awọn enia bayi l'o maa njẹ gbese ti ko nidi. Awọn l'o maa nya owo ta tẹtẹ ti nwọn si maa ndi alaini l'ọjọ ọsẹkọla. Awọn l'o maa nya owo mu ọti ti nwọn yio sọ pe awọn fi npa ironu rẹ ni.

Bi onigberaga enia ko pilẹ ni okowo kan ti o nṣe, yio maa fẹ hoo bi ẹni pe abẹ rẹ ni gbogbo aiye wa.

Bi nwọn fun onigberaga ni owo alupupu nibi iṣẹ, o le lọ ya owo kun un ki o lọ ra mọto aloku. Nigba ti o ba ra aloku ọkọ tan, o tun le lọ yawo lati fi ra ọti jọ, a wa pe awọn ọta rẹ ti ko fẹ anfani fun un ninu idilẹ rẹ jọ pe ki nwọn wa ba oun ṣe ajọyọ ọkọ titun ti oun ra.

Nigba ti onigberaga ba ṣe ohun ti ko to, ti gbese ile ati tode ba di ọran si i l'ọrun, yio wa bẹrẹ si i wa ọna lati yi Naira kan si Naira mẹwa nibi iṣẹ. Ni ipari nwọn a si mu un ninu iwa ole rẹ.

Nigba ti nwon ba wa le e kuro nibi iṣẹ, a wa gbe ọkọ ayọkẹlẹ rẹ ta, a bẹrẹ si i rin ẹsẹ kiri. Nigbati awọn enia t'o ti mọ ọn tẹlẹ ba nri i ni ikọja, nwọn a maa naka ẹlẹya si i.

Onigberaga enia a maa fi iwa igberaga han ninu iwa rẹ gbogbo paapaa ninu ọrọ ẹnu rẹ; idi si niyi ti nwọn fi nsọ pe, okeere rere ni a gbe nmọ ohun onigberaga.

Ẹnu onigberaga na ni onigberaga enia fi maa nko ba ara rẹ. Onigberaga enia le sọ pe, nṣe ni owo oun ti nbẹ nile ifowopamọsi ngbin toripe o pọju. Nipa bẹẹ awọn ọta yio wa bẹrẹ si i da a laamu l'ori ohun ti ko ni.

Onigberaga le sọ pe, oun yio waṣẹ fun enia lai le ṣe bẹẹ. Ọpọ iru wọn l'o maa ngba owo lọwọ awọn alaini pe, awọn yio ba wọn wa iṣẹ lai ni i ṣe bẹẹ.

Nigba ti nwọn ba wa ṣe iwadi rẹ nile iṣẹ wọn, nwọn a wa ri i pe alagbaṣe lasanlasan ni. Nigba ti Ọlọpa ba mu un, awọn enia a wa maa naka si i ni okeere rere pe "A! Onigberaga ni eleyi."

Nigba ti Onigberaga ba nfẹ obinrin, a maa parọ, a si maa sọ pe oun le ṣe ohunkohun. Gbogbo owo oṣu rẹ ni yio maa ko s'apo lati fi ba obinrin sọrọ, ti yio si maa fi gbogbo owo iṣẹ rẹ fa obinrin mọra.

Nigba ti onigberaga enia ba nṣe bayi na owo rẹ danu, ti o si npe ara rẹ ni ohun ti ko jẹ, gbogbo awọn olowo adugbo ni yio si maa pe ni "ẹgbọn" oun ati "baba" oun fun iru obinrin bẹẹ.

Ani, ẹni ti o jẹ pe kẹkẹ lasan ni o tọ si nibi iṣẹ, a si maa sọ fun iyawo ode pe o ku oṣu mẹfa pere ti oun yio gba ọkọ ayọkẹlẹ.

Ṣugbọn nigba ti iyawo ba loyun ti o si de ile, ti ọrọ onigberaga ko si ri bẹẹ mọ, ija a wa bẹrẹ.

Bayi ni iwa onigberaga maa nfa adamu, ti o maa nfa itiju, abuku ati ẹgan ba onigberaga enia.

Ohun ẹṣẹ laarin enia ati Oluwa ni iwa igberaga jẹ nitoripe ninu ohun mẹfa ti Oluwa korira, nitootọ, meje li o ṣe irira fun ọkan Rẹ. Eyi t'o jẹ akọkọ na ni, Oju igberaga: Owe 6;16-19.

Nitorina iwọ Onigbagbọ, jẹ ki o ye ọ pe, bi o ba jẹ onigberaga enia; bi o ti jẹ ọta ara rẹ ni o jẹ ti enia ati ti Oluwa, eyi ti o gajulọ.

L'orukọ Jesu, o tun di ọsẹ t'o nbọ.

ADURA

Oluwa, jọwọ, mu iwa igberaga kuro ninu mi ki emi le ni ireti ninu aiye yi pe, ng o ba Ọ joko nikẹyin nitori Jesu Kristi Oluwa wa, Aamin

## Lati Owo Woli S. I. Owoeye

# Abileko ku sidi awo Ounje

NṢE ni ilẹ daru ni adugbo kan nilu Sapẹlẹ ni ọsẹ ti o kọja nigba ti obinrin abilekọ kan ku sidi awo ounjẹ.

Irohin ti o tẹ wa lọwọ lati Ipinlẹ Bendel fi ye wa pe, ọrọ na ṣe awọn aladugbo ibẹ ni kayeefi pupọ nitoripe nwọn nsọ pe, awọn ko ri i ki iku ṣe bẹẹ pa enia ni igbonagbooru ri.

Irohin sọ pe, bi ọrọ na ṣe jẹ ni pe, nigba ti obinrin na de lati ile iwosan ilu Sapẹlẹ nibi ti o ti lọ gba itọju fun ọmọ rẹ, ni o ba bọ si idi tabili lati jẹ ounjẹ ọsan.

A gbọ pe bi o ti ṣan ọwọ rẹ tan ti o si fẹ bu okele ẹba akọkọ ni o ba ṣubululẹ ti o si ṣe bẹẹ ku bamubamu!

Irohin fi kun un pe lẹsẹkẹsẹ ni nwọn gbe obinrin na, Iyaafin Victoria Awele lọ sile iwosan fun itọju ṣugbọn pabo ni gbogbo rẹ ja si.

A gbọ pe awọn Ọlọpa ti bẹrẹ si i wadi ki l'o fa sababi na, oku obinrin na si nbẹ sibẹ nile iwosan.

# Awako Pijo kosowo Olopa

ỌWỌ awọn Ọlọpa ti tẹ ọkunrin kan ti o fẹ wa mọto Pijo kan wọ ilẹ Idọọmi atijọ (Bini).

Ni oju ọna Ilaro si Owode ni bode Idiroko ni ọwọ ti tẹ ọkunrin na. Awọn Ọlọpa fura pe, boya ọkunrin na ji Pijo 504 na gbe ni.

Ninu iwadi, awọn Ọlọpa ri i pe mọto na jẹ ti Ọgbẹni B. M. C Elhineg ti o nṣiṣẹ ni Godwin and Hopwood Limited nilu Eko.

Nwọn ni ọkunrin na ji Pijo na gbe ni ati pe nigba ti o fẹ fi oru boju gbe e wọ ilẹ Idọọmi ni ọwọ awọn Ọlọpa tẹ ẹ.

Ile iṣẹ Ọlọpa nilu Ilaro ni nwọn mu un lọ lati gba ọrọ silẹ l'ẹnu rẹ ki nwọn to ti i mọlẹ. Iwadi Ọlọpa nlọ lọwọ l'ori ọrọ na.

## IWE ỌRỌ ỌLỌRUN

Fun anfani ẹnyin ti o ṣoro fun lati ri iwe mi yi ra ni ọkọọkan, mo ti ṣeto lati maa fi apapọ iwe na ṣọwọ si nyin ni aadọta Kọbọ (50k) pere.

1. ADURA AIYERAIYE
2. IBANIWI OLUWA
3. KINI ILE AIYE ṢE BAJẸ?
4. Ẹ JOWO ARA NYIN FUN OLUWA

Bi o ba ti fi Postal Order 50k ṣọwọ si mi, ng o fi apapọ iwe na ṣọwọ si ọ lagbara Oluwa, Fi owo ranṣẹ si:

Woli S. I. Owoẹyẹ
Box 1206,
Ibadan.

# ÌSỌ̀RỌ̀-N'ÌGBÉSÌ...

## IPADE (51)

Adeyemọ Ọjẹrinde
MO sọ fun ọ n'Ipade t'o kọja
Ọmọ Ejigbọjọ pe:
Orilẹ-ede t'o ba npọn Oosa le
Ko ni i gbalai maa jiya ẹṣẹ
Nitori agbako t'o dele yi,
Afọwọfa gidi l'o kuku jọ
L'oju iru wa
Nitori bi ko ba si ẹṣẹ
Ojo ko ni i kọ lai rọ.
Nitorina: ọmọ Ejigbọjọ,
Gbogbo Ifa ti ẹ ba ni nile,
Ma gbẹkẹ rẹ le gbogbo wọn;
Bi o ba l'ẹbọra ninu ile nyin
Gbogbo wọn ni o ko sinu omi;
Bi ẹ si l'Oosa Ogiyan,
Ẹ lọ gbe gbogbo rẹ s'odo;
B'o ṣe Eṣu l'ẹ nsin;
B'o ṣe Ṣango Arabanbi;
B'o si ṣe Ọpa Oosa Oko ni;
Gbogbo wọn ni ẹ ko nile
Ki ẹ ko sọ sinu omi;
Gbogbo ere Orisa ni
Ki ẹ ko kuro l'awẹ;
Bi ẹnu rẹ ko ba si tolẹ
Ninu ile ti a bi ọ si,
Ma ṣe ba wọn gbẹkele Oosa wọn
Nitori, kiki ẹṣẹ ṣa
L'o rọ mọ Oosa.

Lawuyi Ogunniran
Otitọ l'ohun t'oo wi, ọmọ Ajiṣegiri;
Otitọ l'o nwi
Ẹṣẹ nbẹ ni Naijiria,
B'ẹṣẹ ba si npọju,
Gbogbo ilu ni i pọn l'oju:
Oun l'a fi nke tantan
Pe, k'a ṣọra, k'a ṣọra
Nitori iya ẹṣẹ nrọdẹde.
O njẹ Naijiria niya.
Ajao ! Inu mi dun
Pe, ori rẹ wale !
Mo woye pe lati ọsẹ diẹ wa,
Ọrọ rẹ mu ni lọkan jọjọ,
Bọya o ko mu agadangidi mọ, ọti agbagba.
Ajao ! Mo faramọ ohun t'oo wi,
Otitọ l'ọrọ rẹ t'oo sọ,
Mo si gbọ imọran t'oo mu wa
L'ori gbigbe Oosa junu.
Mo wa gba 'wọ na n'imọran
Pe, ki o sọ fun gbogbo majeṣin
Ti nbẹ n'ile nyin
Pe, b'o ba di amọdun,
Ki nwọn ma dedi Okeebadan
Nitori mo ranti
Pe, gbogbo wọn lo maa nyọ aṣọ l'eke
Ti nwọn maa nṣẹẹkẹ eebu
Lai ba Oloke tan;
Gbogbo wọn ni o kilọ fun
Ki nwọn ma da s'ọdun oke.
Wayi o, ọmọ Ajiṣegiri,
Ki l'o wa ro pe a ṣe n'ilẹ wa
T'o nbi Ọlọrun Ọba ninu?
Ki l'ẹṣẹ ti a ṣe
Ti ko jẹ k'a r'igba iderun ?
Ki l'o ro pe o fa a,
O sa yẹ k'a mọ
K'a le yẹra dida iru wọn
Nitori k'o ma ba fa iya ba wa
Ni gbogbo Naijiria.

Adeyemọ Ọjẹrinde
Taa l'o fẹ ko ba, ọmọ Ejigbọjọ ?
Taa l'o fẹ k'ọran ba,
Taa l'o fẹ fa s'inu ọran ?
Ẹnu t'aa l'o ti fẹ
Ki nwọn gbọ pe, oju iya Baalẹ fọ?
O kọ mọ pe, aiye fẹlẹ ni ?

Lawuyi Ogunniran
Ṣe nitori pe aiye fẹlẹ
L'o ṣe nṣojo
Ti o ko fẹ sọ otitọ ?
Ṣe, enia l'o nbẹru
Ti o fi fẹ kọ
Lati tọ Naijiria s'ọna ?
O ko mọ pe, bi o ba kọ
Ti o ko ba sọ ọ rara,
Awọn eniyan ko ni i mọ ẹṣẹ yi,
Nwọn ko si ni i le kọ ọ silẹ,
Bi nwọn ko ba si kọ ọ silẹ,
Iya ẹṣẹ ko nii yee jẹ ilẹ wa
Tabi o ha dara k'a wi pe,
Iwọ l'oo ko iya jẹ Naijiria ?

Adeyemọ Ọjẹrinde
Taa l'o fẹ maa tagbọn fun
T'aa lo nba wi,
Taa l'o ntan ?
Bi o ba fẹ mọ idi ọrọ
Tara lọ wadi ninu igboro;
Bi o ba mọ idi tan
Ki o tẹ ẹ fun gbogbo eniyan
Ṣugbọn nitemi ni mo wi
O ko le t'ẹnu mi gbọ nkankan;
K'onikaluku ronuwo
Ki nwọn ro ohun t'o le jẹ ẹṣẹ
Ti a nda, ti nko ba wa ni Naijiria
Ṣugbọn mo fẹ ki o gbọ, ọmọ Ejigbọjọ
Emi ko ni i sọrọ ju eyi
Mo fẹ ki a jawọ l'ori eyi
K'a mu ọrọ miran sọ ni.

Lawuyi Ogunniran
Ṣugbọn, ko dara k'a mẹnu ba ọrọ
K'a ma pari rẹ dele
K'o yẹ k'a mọ ohun ti nfa iya
K'a ma le sọ ọ feeyan gbogbo
K'o yẹ k'a le bẹrẹ ọrọ
K'o ma ni ikilọ
Ti a o ṣe nitori omiran.
Nitorina, a ko le fi
Ori ọrọ yi ti sibikan rara
A o tun ọrọ na sọ dandan.
Emi Ayinde l'o so bẹẹ
Mo si fẹ ki o gbọ s'eti.


## Apprentices Wanted

LEARN to become a successful printer; learn on modern machine with modern technique.

Parents, don't waste the time of your fresh Primary Six & Modern III School leavers; send them to learn modern printing, Machine operating and Book-binding from us. Apply personally today.

The Works Manager,
(Imọlẹ Owurọ)
N4/496B Yemẹtu Aladorin,
Ibadan:


## L. Lawal Tip

**12**
**37**
**40**


IWE IGBAẸLODE DARA PUPỌ, RA TIRẸ NIBẸ

1. Iwe gbogbo Agbo Ọmọde ati Agba 25k
2. Korani ọgọta esu ni ede Yoruba N10 Esu kan (50k)
3. Yasin ni Yoruba ati Isawaka 50k
4. Zabura ati itumọ (N1)
5. Zabura Yoruba (N1)
6. Iwe Aiye Akamara (N1)
7. Iwe Eniaṣoro (N1) Adedẹwẹ (50k)
8. Iwosan Ajẹbidan Ogun enia dudu (N5); Kekere (75k)
9. Iwe ala ni ala (N2)
10. Kekere (50k)
11. Iwe Oogun Iwosan (N2.50) Kekere (75k)
12. Itan Anabi ati Yisa (N1)
13. English Hausa Yoruba & Ibo Registered No 410 (50k)

FI OWO ATI STAMP (5k) RANṢẸ SI:

(1) Alufa Yisa Igbaẹlode N2/394a Odoye Adeoyo Rd, P. O. Box 3365, Mapo—Ibadan.



(2) Alufa Igbaẹlode, Mọṣalaṣi Idi-Işin St, Isalẹ Koto P. O. Box. 17 Ilorin

# Irohin ni Onilujilu

## IKIRUN

O le ni dukia ọlọkẹkan abọ Naira ti o jona ruuruu nibi ijanba ina kan ti o ṣẹlẹ ni ilu Ikirun ni agbegbe Ọṣun ni Ipinlẹ Ọyọ.

Ohun ti a gbọ pe o fa ijanba na gẹgẹ bi Baale ile na, Alagba David Akinọla ti wi fun onirohin wa ni pe, ọkan ninu iyawo ile na ni o tan atupa lanta ti ina si ti ara atupa na gba mọ ile na.

Irohin fi ye wa pe, bi iṣẹlẹ na ti nṣẹlẹ ni nwọn ti ranṣẹ si awọn panapana nilu Oṣogbo, ṣugbọn ki awon panapana ■a to de, ile ti jo kanlẹ.

Bayi, agbọrọsọ kan fun awon enia ilu na, Alhaji Bakare Kondọsile, ti ro Ijoba lati fi ibudo awon panapana si ilu na.

## OBA—OKE

NWỌN ti kede iku Ọlọba-Oke Ọba-Oke ni ẹba Oṣogbo, Oloye Raji Tọmọri.

Aadọrun ọdun ni o lo l'aiye gẹgẹ bi nwọn ti wi.

Ni ọjọ kọkandinlọgbọn oṣu kẹrin ọdun 1960 ni o di Ọla-Oke ki o to tẹrigbaṣọ ni ọjọ kọkanlelogun oṣu kẹta ọdun yi.

Ọpọ ọmọ ati ọmọọmọ l'o gbẹhin rẹ. Ara wọn ni Ọgbẹni Adejare Tọmọri ati Ọgbẹni Raṣidi Tọmọri.

Nwọn ti sinku Oloogbe na gẹgẹ bi ilana ẹsin Islam.

# 4 22

## IWOYE

ILE Igboogun alafoogun oju ara ẹni ko ti awon ara ilu Iwoye nitosi Ẹdẹ nko pẹlu iranlowo awon akẹko mẹtalelogun ti nṣiṣẹ sin orilẹ-ede won fẹrẹ pari.

Nigbati Ọga Onișẹ idagbasoke adugbo na, Ọgbẹni Ọladẹjo Ọjẹdiran nba Onirohin wa soro nibi iṣẹ na laipẹ yi, o ni ile na ti yio na won to ẹgbaaji Naira (₦4,000.00) lati pari, yio di lilo titi ipari oṣu kẹrin odun yi.

Alaga Kansul Ẹdẹ, Ọgbẹni L. O. Ọmotoṣo, wa nibẹ l'ojo na.

## OSI

IROHIN lati Osi ni Kansul Irepọdun ni Ipinlẹ Kwara fi ye wa pe, nṣe ni mọto rẹ okunrin agbẹ kan mọlẹ petẹpetẹ ni nkan bi buṣọ meji si ilu na.

Oko owurọ ni ọkunrin agbẹ na nlọ ki o to kagbako iku moto ti a wi na; ẹsẹ titi ni nwon si ti ba oku rẹ, ati pe nṣe ni awakọ ti o pa a f'ẹsẹ fẹ ẹ.

Irohin fi ye wa pe, awon Ọlopa tilẹ ri akufọ gilaasi ọkọ kan lẹgbẹ oku agbẹ na ti nwọn kọ nọnba ọkọ kan si l'ara; awon Ọlopa si ti nṣiṣẹ l'ori eyi lati mọ bọya l'ara moto ti o pa agbẹ na ni gilaasi na ti jalulẹ.

Bayi, a gbọ pe awon Ọlopa ti gbe oku agbẹ na lọ sile iwosan Omu-Aran fun ayẹwo.

## ILORIN

IROHIN lati ilu Ilorin lati Ipinlẹ Kwara fi ye wa pe Ọba Sokoto, Alaiyeluwa Abubakar ni yio fi ipilẹ Moṣalaṣi Jimo Ilorin lelẹ ni ogbonjo oṣu kẹrin odun yi.

Gẹgẹ bi a ti gbo, Ọkẹ marundinlaadoje Naira (₦2,500,000.00) ni nwon yio fi ko pe Moṣalaṣi na.

A o ranti pe lati opolopo odun sẹhin ni ilu Ilorin ti nlakaka lati ko Moṣalaṣi Jimo si ilu na ti ko ti i ṣe iṣe.

Ọpolopo enia nlanla ni a gbo pe nwon ti pe lati ba won ṣe ayẹyẹ fifi ipilẹ Moṣalaṣi na lelẹ.

# 4 12 43 51

## ABEOKUTA

GBAGADA ni obinrin abileko kan, Saratu Aro busẹkun nile ẹjo Adiyeloja nigba ti o gbo pe ẹgbẹrun Naira ni owo itanran ti oun yio san fun jijẹbi ẹsun ere ajẹju.

Saratu Aro ti o ngbe Adatan ni Abẹokuta ni awon afẹsunkanni fi ẹsun kan pe o ta paali oti kan ni Naira mẹwa fun okunrin kan ti njẹ Nureni Popọola ni ojo kẹedogun oṣu kinni odun yi dipo Naira mẹfa ati aadorin kobo ti awon Adiyeloja palaṣẹ.

Adajo ile ẹjo na, Ọlola Ọdunlami da obinrin na lẹbi o si paṣẹ pe ki o lo sanwo itanran.

Irohin fi ye wa pe nigbayi ni obinrin na jade ti o si so pe "Ṣe ogorun Naira ni, ng o san an". Ṣugbon nigba ti Akowe ile ẹjo na so fun un pe, ẹgbẹrun Naira (₦1,000.00) ni Adajo palaṣẹ pe ki o san, ki i ṣe ogorun Naira (₦100.00), ni obinrin na bu gbagadasẹkun pe, nibo ni oun yio ti ko o!

# 3 6 9 37


## Yasin ati Isawaka

EYI ni lati kede fun ẹnyin onibara wa ti ẹ ti nkowe si wa lati ọjọ pipẹ pe, a ti ni Yaasin ati Isawaka ni ede Yoruba ati Wutuba rẹ.

Adura pataki ni fun Musulumi. 50k ni Ẹyokan, ₦2. ni Dosinni rẹ.

Tete fi owo ranṣẹ si:-

Alufaa Igbaẹlode
(1) N2/394A Odoiye
Adeoyo Rd,
P. O. Box 3365
Mapo, Ibadan

(2) Alufaa Igbaẹlode
Moṣalaṣi Idi Iṣin St;
Iṣale Koto,
P. O. Box 17
Ilorin



## NIGERIA NEW STATES CO.

Jẹ atẹwe asiko. Bi o ba fẹ tẹ oniruuru iwe: Kalẹnda, Almanak ati bẹẹbẹẹ lo, Ile Iṣẹ wa wa ni:

18, Ọdunlami Street,
Phone 27017, Lagos.


# Ẹgbẹ Imọlẹ Owurọ

- 12,460 Yinusa Ralesh Gbongan
- 12,461 Rasaki Kazeem, Ibadan
- 12,462 Amusa Ọlaiya, Ilala
- 12,463 Akangbe Ọnaolapo, Ogbomoṣo
- 12,464 Kolawole Gbadamoṣi, Ibadan
- 12,465 Bodunrin Alo, Alo
- 12,466 Oloye Bola Ọlaleye, Eruwa
- 12,467 Fẹmi Abikoye, Ijomu - Oro
- 12,468 Yakubu Motolani, Eko
- 12,469 Mosudi Olurebi, Muṣin
- 12,470 Mudaṣiru Okunlola, Ifẹ
- 12,471 Kolawole Amoo, Ẹdẹ
- 12,472 Sikiru Kolapo Ibadan
- 12,473 Yusuf Ajenikoko, Ibadan
- 12,474 Ọlaiya Owolabi, Aawẹ
- 12,475 Karimu Azeez, Eko
- 12,476 Ọlaniyi Ajayi, Ibadan
- 12,477 Ọlaniyi Adewara, Esiẹ
- 12,478 Mufutau Balogun, Ileṣa

FUN IGBEGA EDE ATI AṢA YORUBA DI

**Omo Egbe Imole Owuro**

(Iwe Idi Ọmo Ẹgbẹ)

Orukorẹ.....................................................

Adirẹsi rẹ....................................................

Ọmọ Ilu ti o jẹ..............................................

Jawe yi ki o si poosu rẹ si
DOKUN AJADI
(Akowe Ẹgbẹ)
P.M.B. 5230, Ibadan.

# Ẹgbọ t'emi

## E jawo nibi ila kiko

OLOOTU,
GBA mi l'aye lati kesi awon enia wa ni ilẹ Yoruba paapaa ni Ipinlẹ Ọyọ lati fi opin si ila kiko s'oju omo nitoripe oju ti la, aiye ko kola mo.

O ya mi l'ẹnu pe opolopo enia ni awon ilu bi Ibadan, Ọyọ, Iwo, Oṣogbo, Ẹdẹ, Ejigbo, Ogbomoṣo, Ṣaki, Isẹyin, Okeho, Iganna, Igboho, Ibarapa, ati bẹẹbẹẹ lo ni awon si tun nko omo won nila oju.

Awon idile miran tilẹ kojalẹ lati fi opin si ila oju kiko, awon miran nko akobi omo won nikan nila.

Ṣugbon l'oju temi, emi ko ri anfani kan ti o wa ninu ila kiko ni ode oni mo; o si yẹ ki a jawo ninu apon ti ko yo, ki a da omi ila kana.

Ko ju bayi lo, Olootu. Ajinde ara yio maa jẹ o.

Emi ni,
Jẹnrade Omo Kilanko,
Ọyọ

## Olowo Ojiji

OLOOTU,
O pẹ ti mo ti maa ngbo ti awon enia maa ntoka si iru awon enia kan gẹgẹ bi "Olowo ojiji".

Iru awon enia ti a nwi yi a maa lowo lowo daadaa, nwon a si maa gun moto ayokẹlẹ olowo ribiribi.

Olootu, ohun ti ko wa ye mi ni, ohun ti awon enia ri ti nwon fi npe won bẹẹ. Ṣe ki i ṣe inunibini l'o fa a ? Tabi ilara ni ?

Emi ni,
Isiaka Karitowoṣe

Muṣin
AKIYESI
Ọgbẹni wa Isiaka,
Ki iṣe bi ẹ ti ro o si nni l'o jẹ. Ẹnikẹni ti omo araiye ba ri ti o nda bi ẹdun, ti o nro bi owe lojiji lai mo iṣẹ pataki kan ti iru ẹni bẹ ṣe di titobi, ni omo araiye maa npe ni "Olowo ojiji".

Ni kukuru, omo araiye gbagbo pe ti ki i ba ṣe pe ẹnikan jẹ tẹtẹ, bi iru ẹni bẹ ba lowo ojiji, nwon a ni, ona aito l'o gba ni i.

— OLOOTU

POOLS! POOLS!!

Alabi Nap

4 7 24

Tajudeen Tip

8 25 36

Alade Tip 12 33 46

# E nba Wundia l'oruko je

OLOOTU
MO ka a ninu iwe nyin osẹ ti o koja ti okan ninu onkawe nyo pe, Wundia ti tan l'aiye; o fi awon Sisi Naijiria we aja, o si so pe, o sanfani lati fẹ adelebo ju omoge iwoyi lo.

Mo fẹ ki ẹ gba pe, ibalorukojẹ ati aimokan gidi ni eyi jẹ. Bi kii ba ṣe bẹẹ ni, o yẹ ki ẹ le mo pe, omobinrin yowu ti ko ba tii dele oko ni awon npe ni wundia. Bawo lẹ ṣe wa nba wundia ni oruko jẹ bẹẹ?

Emi ni,
Alice Ayoola,
Eko

AKIYESI
Ọrẹ wa Alice,
Ki iṣe pe awa tabi onkawe na ba wundia l'oruko jẹ rara. Ero okan tirẹ l'ori awon wundia ode oni l'o so, o si l'ẹto lati soro.

Ṣugbon imoran tiwa fun awon Wundia ode oni ni pe: "Bi a ba pe ni ni abifun rairai, nṣe ni a pa ifun ohun mo."

—OLOOTU

## Mo faramo aba nyin

OLOOTU,

NI osẹ kẹta sẹhin ninu Imolẹ Owuro ni onkowe kan so bi igbo mimu ṣe npo si i ni ilẹ Naijiria paapaa lẹnu igba ti Ijoba Apapo din ẹwon amugbo ku si oṣu mefa lati odun mẹwa.

Nitooto ni oro na pe amugbo npo si i, eyi l'o si jẹ ki iwa ifipajale ipaniyan rogbodiyan nile iwe ati jagidijagan awon omode gbogbo maa gbodekan nilẹ wa.

Nitorina, mo faramo aba onkawe na pe ki Ijoba Apapo da ofin amugbo pada si odun mẹwa fun ẹni ti o ba jẹbi. Awon amugbo awamoto l'o npa enia puu-puu bi ẹran.

Emi ni,
R. A. Ayanwale,
Ogbomoṣo.

KEREO
GBOGBO - ENIA!
fun
•Ipolowo oja ati Ikede,
•Akiyesi ati Itufọ,
•Iranti oku ati Ikede Ariya,
•Ikilọ ati bẹbẹ lọ;
•Tabi Almanak ati Kalẹnda titẹ.

DARAPỌ PẸLU AWỌN ỌLỌGBỌN ENIA TI O NṢEE SI INU (IMỌLẸ OWURỌ) TI O GBAJUMỌ KARI AIYE. OWO TI A NGBA KOPỌ, SA KỌWE TABI KI O WA RI :-

Advertisement Manager:

IMỌLẸ OWURỌ
N4/496a YEMETU ALADORIN,
P.M.B. 5230, IBADAN.

# Oyedemi di Baale Akeetan

NWỌN ti fi ọkunrin olowo – apo ẹni ọdun mejilelogoji kan, Ọgbẹni Gbadamọṣi Ọladẹjọ Oyedemi, jẹ Baalẹ Akeetan nilu Ọyọ.

Awọn Iwẹfa Alaafin Ọyọ labẹ Ọna–Ẹfa, Oloye Belo Afọlabi l'o jawe oye le Baalẹ titun na l'ori ni gbongan Aganju, Aafin Ọyọ.

Oloye titun na l'o rọpo Baalẹ ana, Oloye Ṣanusi Ọladoye, ẹni ti o filẹ bora bi aṣọ ninu ọdun 1974.

Baalẹ Oyedemi Keji yi ni Baalẹ kẹwa ti a o fi joye Baalẹ Akeetan lati igba ti Alaafin Atiba ti gbe ijoko Ijọba rẹ kalẹ ni Ọyọ isinsinyi.

# Are asaju l'o nfa ijanba moto



ỌGAGUN IKPẸMẸ
Gomina Ondo

ỌGA Ọlopa Ipinlẹ Ondo, Ọgbẹni Aboyade Cole ti so pe, are asaju ni o nfa opo ijanba moto ti o nṣẹlẹ l'oju awon ona wa gbogbo.

Nilu Akurẹ ti iṣe olu ilu Ipinlẹ na l'o ti soro yi ninu osẹ ti o koja.

Ọga Ọlopa na so pẹlu pe, awon awako buru tobẹẹ ti o fi jẹ pe, nwon ki i bikita fun ofin irinna gbogbo, bẹẹ ni nwon ki i pa ikilo ti awon Ọlopa ba ko sara pako mo.

Nigbana ni Ọga Ọlopa na kilo gidigidi fun awon awako ni Ipinlẹ na lati jawo ninu are isakusa ati lati ṣora nibi aika ofin irinna si nitori nwon nti ipa bẹẹ fi ẹmi enia ṣofo pupo.

Ọga Ọlopa na so pe, awako yowu ti owo ba tẹ l'ori hihuwa buburu na, yio mo pe, aiye pe meji.

## Ta l'o ni iwe yi lowo ?

A nfẹ ki ẹkikẹni ti o ba ni iwe atijọ yi lọwọ, ti o si fẹ ta a, ki oluwarẹ tete kọwe si wa ki o si sọ iye ti o ba fẹ ta iwe na.

Iwe na ni RIGIMỌ OBINRIN KO ṢE TU tabi AIYEJỌKẸ A RI ỌGBỌN DARA.

O to ọdun mẹẹdọgbọn bayi ti nwọn ti tẹ iwe na jade.

Ki ẹnikẹni ti o ba ni iwe na lọwọ tete kọwe si wa, ki oluwarẹ si kọ adirẹsi ti a 6 le ri oun sinu iwe na pẹlu iye ti o ba fẹ ta iwe na. Kowe tabi ki o mu iwe na wa si odo:

L. A. Babalọla,
18, Ọdunlami Street,
Lagos.

**Nap 1 8 38**

FOR ALL YOUR

Electronics

Fans, Cookers, Radio sets, T.V. Colour T.V. sets, coolers etc: at resonable prices

PATRONIZE

Aiyedetisola Commercial Electrical Store:

AN27 I.C.C STALL
AGODI GATE
IBADAN

# Igbeyawo Remi ati Wura Koyoyo

ẸNUKỌ-IROHIN ni ayẹyẹ igbeyawo laarin Omidan Wuraọla ati Arakunrin Remi Adekunle, eyi ti o waiye ni ojule kejilelọgbọn Opopo Modupẹ Johnson ni adugbo Surulere nilu Eko ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ keji oṣu kẹrin ọdun yi.

Ọpọlọpọ enia nlanla jakejado ilẹ Naijiria ni o wa sibi ayẹyẹ igbeyawo na.

Ninu ọrọ isinileti ti o sọ nibẹ, Alawọ ilu Awọ—Ekiti ni Ipinlẹ Ondo, Alaiyeluwa Samuel Ọlanipẹkun sọ pe, o yẹ ki igbeyawo laarin okunrin ati obinrin maa ni ọla nitori ohun pataki ni igbeyawo jẹ niwaju Ọlọrun Ọba paapaa.

Ọba na so pe, bi igbeyawo ba lọla laarin tọkọtaya, ifẹ, ifẹkan—tanraẹnitan ati alaafia yio wa ninu ile wọn, igbeyawo wọn yio si l'ayọ.

Kabiyesi fi kun un pe awọn tọkọtaya na ni lati ni ifẹ ara wọn denu ki nwọn ma si ṣe gba ẹṣu l'aye laarin ara wọn toripe "iku ọkọ nbẹ lọwọ aya, bẹẹ ni idaamu aya nbẹ lọwọ ọkọ"

Nigbana ni Kabiyesi sọ nipa ẹbi ọkọ ati ẹbi iyawo bi o ṣe ṣe pataki to lati maṣe jẹ ki ajọṣepọ ti o wa laarin wọn bajẹ. O ni bi ija ba tilẹ wa laarin ọkọ ati iyawo, ohun ti o dara ni ki ẹbi mejeeji maa ba wọn pari ija, ki nwọn si ri i pe, ile tọkọtaya na toro nigbagbogbo.

Ki Kabiyesi na to pari ọrọ rẹ, o fi idunnu rẹ han si ifẹ pataki ti o wa laarin ẹbi mejeeji ti o fi ọmọ fun ara wọn, o si gbadura ki ifẹ na wa pẹ titi.

Bakanna ni Kabiyesi wa kesi awọn ọdọmọkunrin ati ọdọmọbinrin ni ilẹ wa lati nifẹ si ṣiṣe igbeyawo ti o lọla bi iru eyi

Ara awọn enia ti o wa sibi ayẹyẹ na ni: Ogbeni A. A. Ariyibi, Iyaafin F. B. Ọlaọrẹ, ẹni ti gbogbo enia mọ bi baba ati iya fun iyawo na nipa iwa rere ati ikonimọra, Madam Adepeju Ariyibi, Oloye Aṣasa, Alhaji Aṣani, Oloye Adekunle ti iṣe baba ọkọ iyawo, Ojiṣẹ Ọlọrun Ilesanmi ti iṣe ẹgbọn ọkọ iyawo, Ọgbẹni Toye Owoẹyẹ ti oun na jẹ ẹgbọn ọkọ iyawo, Iyaafin Adeyinka Adebayọ ti oun na jẹ ẹgbọn ọkọ iyawo, Iyaafin Adeoti Ọdẹremi ati Olu Adekunle Isti ilu Ọba.

# Gbomogbomo fe ji Dokita gbe

gbe e, ṣugbọn Dọkita na kọjalẹ pe oun ko !e tẹle wọn lọ ninu Takiṣi nitoripe gẹgẹ bi ofin, mọto Anbulansi ilewosan ni nwọn fi gbọdọ wa gbe Dokita nile fun iṣẹ pajawiri ọganjọ oru

A gbọ pe, bayi ni Dokita na kọ lati ba awọn "Gbọmọgbọmọ" na lọ, ti aniyan wọn lati ji i gbe si ja si asan.

Irohin fi ye wa pe, awọn Ọlọpa ti mu awọn enia kan ninu oṣiṣẹ ile iwosan na fun iwadi.

Bakanna ni Alakoso Eto Ilera ni Ipinlẹ Ogun Ọgbẹni Olumade Adeuja sọ pe, ododo ni irohin na ati pe Ijọba Ipinlẹ Ogun ti bẹrẹ si i ṣe iwadi l'ori ọrọ na.

## AKIYESI

EYI ni lati tọrọ afọrji lọdọ enyin onkawe wa pe, ile iṣẹ NEPA ti o mu ina lọ ni ko jẹ ki a jade l'ọsẹ t'o kọja.

Bayi, Imọlẹ ti tun de o, ki Okunkun parada.

—OLOOTU


# OLORIRE O! OLORIRE O!

AWA ẸGBẸ ONIṢOWO ONIṢẸ ẸRỌ TI NJẸ

**WESTERN NIGERIAN TECHNICAL COMPANY LTD**

NI A NKE SI NYIN.
KI L'O ṢE Ọ—IWỌ OLUGBAṢẸ ILE KIKỌ?
KI L'Ọ ṢE Ọ—IWỌ KỌLEKỌLE?
KI L'O ṢE Ọ—IWỌ ONIṢOWO?
KI L'O ṢE Ọ TI O ROJU KOKO?
TABI O KỌLE DIGBESE NI?
A ! O MA ṢE O!!
KI L'O ṢE TI O KO RỌJU WAA RA
ẸRỌ WA YI—



**Block Making Machine**

9 x 9 x 18 N300.00

6 x 9 x 18 N300.00

(EYI NI ẸRỌ TI NYỌ BULỌỌKU LORIṢIRISI IWON A NI 9 x 9 x 18 ati 6 x 9 x 18 (SIZES) FUN TITA BI O BA TI NI ẸRỌ YI LỌWỌ MA FOYA MỌ, IDẸRA TI DE FUN Ọ OWO RẸ KO PỌ RARA, ₦300.00 PERE NI.

Bakanna ni a tun ni oriṣiriṣi ẹrọ ilọta "BECO" fun tita pẹlu. Sa ma jafara, tara maa bọ pẹlu Imọlẹ Owurọ kan ti a polowo ẹrọ yi si ninu lowo rẹ si:

**Western Nigerian Technical Company Limited**

P.M. B. 5148: PHONE 22361/2
DUGBE ONIMATIRESI, IBADAN


Printed and published by the People's Star Press Limited [illegible]